# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**Oṣù Kejì, Ọdún 2024**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**(ÌSÌN ỌRẸ ÀKỌ́SO)**

**OṢÙ KEJÌ, ỌDÚN 2024**

1. **Èmi 'ba n'ẹ́gbẹ̀rún ahọ́n,**

Ògo f'órúkọ Olúwa,
Ògo Ọlọ́run Ọba mi,
Ògo f'órúkọ Olúwa!

Ògo f'ókọ Rẹ̀, Ògo f'ókọ Rẹ̀,
Ògo f'órúkọ Olúwa,
Ògo f'ókọ Rẹ̀, Ògo f'ókọ Rẹ̀,
Ògo f'órúkọ Olúwa.

2. Jésù t'ó sẹ́rù wa d'ayọ̀,

Ògo f'órúkọ Olúwa
Orin ni l'étí ẹlẹ́ṣẹ̀,
Ògo f'órúkọ Olúwa!

3. Ó ṣẹ́gun agbára ẹ̀ṣẹ̀,

Ògo f'órúkọ Olúwa,
Ẹ̀jẹ̀ Rẹ̀ le w'elérì mọ́,
Ògo f'órúkọ Olúwa!

4. Ó sọ̀rọ̀ ayé gbóhùn Rẹ̀,

Ògo f'órúkọ Olúwa,
Oníròbínújẹ́ y'ayọ̀,
Ògo f'órúkọ Olúwa!

5. Odi, ẹ kọrin ìyìn Rẹ̀
Ògo f'órúkọ Olúwa
Afọ́jú, Olùgbàlà dè,
Ògo f'órúkọ Olúwa

6. Bàbá mi at'Ọ́lọ́run mi
Ògo f'órúkọ Olúwa
Kí nlè rò ká gbogbo ayé
Ògo f'órúkọ Olúwa

**1. Krístì Balógun wa níwájú ogun,**
B'ó bá rán wa n'íṣẹ́, a kò ní bẹ̀rù,
Bí ohun t'Ó fẹ́ ṣe kò tilẹ̀ yé wa,
Síbẹ̀ aó tẹ̀lé títí.

Tẹ̀ síwájú l'áṣẹ Olúwa,
Tẹ̀ síwájú sí'lẹ̀ 'lérí nà,
Tẹ̀ síwájú kọ orin sókè,
Pẹ̀lú Krístì, ìṣẹ́gun dájú.

2. Gbogbo ìfẹ́jú èṣù kò lè mì wá,
Bí Krístì jẹ́ asà àt'àpáta wa,
Aó ma fi idà ẹ̀mí bí a tí nlọ,
A ó ma tẹ̀lé títí.

3. Ẹ jẹ́ kí a gbé àsía ´wa s'ókè,
Ibi kò lè dé ibití ó bá wà,
Krístì, Balógun wa ti ṣẹ́gun ayé,
A ó ma tẹ̀lé títí.

4. B'ógun ná tilẹ̀ le, kò ní pẹ́ parí,
Nígbàná, aó dàpọ̀ pẹ̀l'áwọn mímọ́,
Láti fi ayọ̀ kọ orin ìṣẹ́gun,
Bí a ba tẹ̀lé títí.

## <u>Ọ̀RỌ̀ AGBÁRA</u>

1. Ìwo òkùnkùn ìyówù, tí wọ́n yàn láti ti àwọn ilẹ̀kùn mi l'ọ́dún yìí, kí n tó kúrò níyìn, ìwọ yóò túká sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.
2. Lónìí, nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, èmi yóò gba ifòròróyàn fún ìyára kánkán atòkèwá, ní orúkọ Jésù.
3. Ohun rere ìyówù nínú ayé mi tó ti gbàbọ̀dè, gbọ́ Ọ̀rọ̀ Olúwa, ìwọ yóò gba ìyè lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo ìhámọ́ra òkùnkùn, tí wọ́n ṣe lòdì sí ìyára kánkán mi atòkèwá l'ọ́dún yìí, yóò gbiná lónìí, ní orúkọ Jésù.
5. Bàbá mi àti Ọlọ́run mi, jẹ́ kí gbogbo ìlọ́wọ́wọ́ nínú ìgbé ayé ẹ̀mí mi gba agbára àjínde lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Nípa agbára tó pa Gòlíátì, Ọlọ́run mi yóò pa gbogbo ìjákulẹ̀ tí wọ́n ṣe lòdì sí àwọn ilẹ̀kùn mi tó ṣí sílẹ̀ l'ọ́dún yìí, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo agbára tí wọ́n yàn láti fa àwọn ohun rere mu kúrò nínú ayé mi l'ọ́dún yìí yóò ṣubú lulẹ̀ kú lónìí, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**ÌJẸ́WỌ́ - ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo ìròyìn sátánì láti tú ìyára kánkán mi atòkèwá ká l'ọ́dún yìí, gba iná, ní orúkọ Jésù.
4. Àwọn agbára tí wọ́n yàn láti jẹ́ kí n wọ́ lọ sí ilẹ̀ ìlérí mi l'ọ́dún yìí, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo agbára òkùnkùn tí wọ́n gbà, láti fòpin sí ẹ̀mí mi l'ọ́dún yìí, pa àwọn tó ni ọ́, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn ète ìkà tí wọ́n yàn lòdì sí ayànmọ́ mi l'ọ́dún yìí, padà sọ́dọ̀ àwọn tó rán ọ, kí o sì pa wọ́n run, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo agbára olóríkunkun t'ówà nídì iṣòro ayé mi ìyówù, kí àṣírí wọ́n tú, kí wọ́n sì gba itìjú lónìí, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ ỌRỌ̀ NÁÀ

**I Jòhánnù 2:14** Èmi kọ̀wé sí nyin, ẹ̀nyin bàbá, nítorítí ẹ̀nyin ti mọ̀ ẹnití ó wà lí àtètèkọ́ṣe. Èmi ti kọ̀wé sí nyin, ẹ̀nyin ọ̀dọ́mọkùnrin, nítorítí ẹ̀nyin lí agbára, tí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run sì dúró nínú nyín, tí ẹ sì ṣẹ́gun ẹni búburú ni.

**Orin Dáfídì 126:5** Àwọn tí nfi omijé fun ìrúgbìn yóò fi ayọ̀ ka.

**Orin Dáfídì 119:111** Ẹ̀rí Rẹ ni ogún mi láíláí: nítorí àwọn li ayọ̀ inú mi.

**Òwe 17:22** Inu-dídùn mú ìmúláradá rere wá: ṣùgbọ́n ibìnújẹ́ ọkàn mu egungun gbẹ.

**3 Jòhánnù 1:4** Èmi kò ní ayọ̀ tí ó pọ̀jù èyí lọ, kí èmi kí ó ma gbọ́ pé, àwọn ọmọ mi nrìn nínú òtítọ́.

**2 Kọ́ríntì 6:10** Bí ẹnití ó kún fún ibìnújẹ́, ṣùgbọ́n àwa nyọ̀ nígbàgbogbo; bí tálákà, ṣùgbọ́n àwa nsọ ọpọ̀lọpọ̀ di ọlọ́rọ̀; bí ẹnití kò ní nkan, ṣùgbọ́n àwa ní ohun gbogbo.

**Oníwàsú 9:7** Ma bá tìrẹ lọ, ma fi ayọ̀ jẹ oúnjẹ rẹ, kí o sì ma fi inú-dídùn mu ọtí-wáínì rẹ: nítorípé Ọlọ́run tẹ́wọ́gba iṣẹ́ rẹ nísisìyí.

## ÀDÚRÀ ṢÍWÁJÚ FÍFI ỌRẸ ÀKỌ́SO RẸ SÍLẸ̀

**Na ọrẹ rẹ sókè, kí o sì gbàdúrà báyìí:**

"Bàbá, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ fún fífún mi ní anfàní, okun àti ọgbọ́n láti ní ọrẹ irúgbìn yìí. Pẹ̀lú ọrẹ yi, mo dámọ̀, mo si yìn Ọ́ gẹ́gẹ́ bí orísun kànṣoṣo ti ìṣúná mi. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ nítorí nígbà kan rí mo ti sọnù, ṣùgbọ́n a ti ṣàwárí mi báyìí. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ fún igbàlà ọkàn mi.

Bí mo ti n fi ọrẹ àkọ́so yì sílẹ̀ báyìí, tẹwọgbà á , Olúwa, nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù. Nípa ọrẹ yìí, mo jẹ́wọ́ wí pé, Ìwọ ni olú àníyàn mi. Ọlọ́run, dìde, kí o si lo ọrẹ yì gẹ́gẹ́ bí kọ́kọ́rọ́ sí ipọ̀si, títóbi, ìgbéga àti ojúrere mi tíkò wọ́pọ̀. Nípa ọrẹ yìí, jẹ́ kí gbogbo agbára afiniṣòfò gba ìparun kúrò nínú ayé mi. Gbà mí kúrò nínú àdánù yòówù, kí O sì fi àwọn ibùkún tí owó k'òlè è rà gbé ayé mi wọ̀.

Nípa ọrẹ yìí, mo de ara mí mọ́ orísun ètò ìṣúná owó ti ọ̀run tó ṣí sílẹ̀, alàjá tíkòwọ́pọ̀, ìṣerere tó n jẹgàba, ojúrere tíkòwọ́pọ̀, aṣèyọrí tó tayọ eròngbà àti ìṣẹ́gun pátápátá, ní orúkọ Jésù.

Bí mo ṣe n fi ọrẹ àkọ́so yìí sílẹ̀, jẹ́ kí agbára iyàsì-mímọ́ rẹ ṣàn sínú àwọn ètò iṣùná mí tókù. Olúwa, gbé mi wọ inú ibi, ipò, ifòròróyàn àti ọgbọ́n àtòkèwá Rẹ fún ayé mi. Jẹ́ kí wàrà àti oyin ilẹ̀ yìí dí gbígbìn si óókan-ayà mi.

Èyí ní mo gbàdúrà, ní orúkọ nlá Jésù Kristì Olúwa. Àmín.”